# IROHIN LATI GBEGBE

IJEBU - JẸṢA.
## AJỌDUN ẸGBẸ BIṢỌBU MINRINGINDIN

Ni ọjọ ọsẹ ọjọ keji oṣu kewa ọdun yi ni awọn ẹgbẹ Bishop ni Ilu Ijẹbu jẹṣa lọsi ile ijọsin CMS lati ṣe ajọyọ isin Ajọdun wọn ti wọn ma nṣe lọdọdun.

Ajọdun yi bẹrẹ ni dede nkan bi agogo mẹsan abọ owurọ pẹlu orin 566. Lẹhin eyi, Ọgbẹni Benjamini oniṣẹ Ọlọrun lati Ẹrẹ bẹrẹ pẹlu adura ati aṣayan ọrọ ninu iwe adura. Lẹhin na, Ọgbẹni I. D. A. Wilberforce, ẹniti o ma nran Alufa Ijọ lọwọ ninu siṣe Iṣẹ Ọlọrun lojọ isimi ka adura pataki fun isin Ajọdun na.

Lẹhin orin 552, Alufa ṣe ifilọ fun awọn Ijọ. Nigbati Alufa Ijọ, Rev. D. A. Yọloye ṣe ifilọ tan ni awọn ọmọ ẹgbẹ kọ orin aladun meji fun awọn ti o wa ba wọn ṣe aṣeyọ na.

Lẹhin eyi awọn ọmọ ẹgbẹ na ṣe idupẹ fun ẹmi wọn ti o tun mọ ọjọ Ajọdun ti ọdun yi. Alufa D.A Yọloye loṣe iwasun ajọdun na. Ninu ọrọ iyanju na, o fẹnu ba itọju ọmọ wọn ati bi a ti ṣe nhuwa ti o dara ni ile ẹni, ilu ẹni, larin ẹgbẹ ẹni, ati larin Ijọ. Lẹhin iwasu ni Arabirin Yọloye fun ijọ n irohin ipade ti wọn lọ ṣe ni Ileṣa. Lẹhinna niwọn mu isin Ajọdun na wa sopin nipa kikọ orin 561. Wọn si jade ninu Ile Ijọsin na lẹhin ti Alufa Ijọ ṣe ore-ọfẹ.

Awọn Ẹgbẹ Bisọbu to lọwọwọ lati iwaju Ile ijọsin titi lọsi ile Ẹgbẹ wọn ni Ọgbọn Ilọrọ ni ile Oloye Walaiye. Nibẹ ni jijẹ ati mimu ti bẹrẹ lati nkan bi agogo mọkanla abọ titi o fi di nkan bi agogo mẹta osan.

Nwọn yọ ayọ Ajọdun wọn na titi di alẹ ọjọ na.

Pupọ awọn ti o wa ba wọn ṣe Ajọdun na wa lati Ẹrẹ ati Iwoye. Diẹ ninu awọn enia pataki ti o wa ninu ile Ijọsin Ajọdun na ni Ọgbẹni I. A. Ọkin lati Ilọrin, G. F. A Arowobusoye, Orimoniyi, Fajojuto. Oloye Saba, Oṣogun, Ọgbẹni Adeniran (Aluduru) Akande, S. D. Owotori, Adewumi, Daramọla, Councilors B. O. Orioke, I. D. A Wilberforce, J. B Ajiwumi, Awẹ, S. O. Ọla ati bẹbẹ lọ titi.

## IṢẸ TI ỌLỌRUN RAN MI
(Lati ọwọ Apositeli M. O. Isamuko New Ikeji)

Jọwọ Olotu, mo fẹ ki o gba mi ni aye diẹ lati jiṣẹ kekere yi fun gbogbo enia Iṣẹ ti Ọlọrun ran mi si gbogbo aiye.

Oluwa ni ki gbogbo enia ma gbadura leri ohun mẹta ki ọdun to de.

(1) Oluwa ni ki a ma gbadura pe, ki a maṣe riku akudọmọnu larin awọn obirin.

(2) Eṣu tun wewe pe, ọpọ ọkọ ti o nlọ si ebute ni on yio danu.

(3) Oluwa ni aisan oju didun yio pọ. Ṣugbọn ki a gbadura si Ọlọrun pe ki on le ba wa ṣẹgun eṣu.

Ki ẹ wo Iwe Luku 18 verses 1-2; Mika 6 verses 8-9; Jobu 5 verse 27.

Olotu ki Oluwa jẹ ka fi ara rere ṣọdun o Amin.

## IRANTI BABA ẸGBẸ TI N.C.N.C.
(Lati ọwọ John Ayọdele K 44 Anaye, Ileṣa)

Mo ki Olotu ati awọn osiṣẹ ẹgbẹ yi mulẹ to si jẹpe lori Irawọ Obokun. Obokun a ran irin soke irin sodo rẹ ni ọlọjọ yin lọwọ o, yio si ba yin tu iṣẹ de ba. yin ṣe.

Ọrọ kekere yi ni mo ronu si ti mo si rope o tọ, o yẹ ki ẹgbẹ NCNC le ṣe ohun ti mo rope o yẹ ki gbogbo ẹgbẹ NCNC jakejado Nigeria le yan ọjọ kan pataki lati ma fi ṣe iranti baba ẹgbẹ wọn akọkọ, ki eleyi le ma wu ọpọlọpọ lori ki o si le fi han pe a ko gbagbe rẹ. Eleyi ni Herbert Macaulay ẹniti o jiya to si ṣe ọpọlọpọ wahala nipa fifi ẹsẹ

Mo si tun fi ọrọ yi le ẹnyin alakoso ẹgbẹ yi lọwọ lati maṣe sọ ọrọ mi yi danu. Ati ki awọn to ni ifẹ ati itẹsiwaju ẹgbẹ yi lọkan jiroro leri ọrọ mi yi ki ẹ ma si ṣe sọnu, ki ẹ ba mi gbiyanju ki ọrọ na le jade ni inu iwe Daily Time ki gbogbo Nigeria ati Comeroon ba le gbọ jake jado. Nitori on to le yewa bi eyi, o si yẹ kale ṣe ki Ọlọrun ko ran gbogbo wa lọwọ o. Amin.

## MO DUPẸ LỌWỌ ỌLỌRUN
(Lati ọwọ Prophet James)

Inu mi yio dun bi oloto bale gba mi laye nina iwe rẹ oloyin mọmọ lati fiki awọn Obokun nile ati agbegbe ati idalẹ wipe wọn ku ile o.

Alafia fun nyin ẹnyin ọmọ Obokun mo dupẹ pupọ lọwọ Ọlọrun fun idari ẹmi mimọ Rẹ to ri mi ni ẹlẹṣẹ, to tun ka mi kun ọkan ninu awọn ọmọ lẹhin rẹ lati maṣe iwasu Ihinrere rẹ kekiri. Ki Ọlọrun maṣe gbogbo wa ni Judasi. Amin.

Lati ọjọ kẹta oṣu kọkanla ọdun 1954 ni mo ti dide irin ajo nida iṣẹ Oluwa lọsi awọn ilu wọnyi Irẹsi, Iragbiji, Ikoro, Ipoti Ido Irun.

Mo dupẹ pupọ Oluwa si ṣe iṣẹ rẹ lọna iyanu ọpọ awọn aguntan wọ agbo, ọpọ awọn agan di ọlọmọ, alabiku nbi abiye, alaisan ri iwosan. Bayi ni mo ṣe rin irin ajo na, nipa ti Oluwa

Ni ọjọ karundogun oṣu kẹjọ ọdun yi ni Oluwa tun da mi pada si aye mi ni ilu Oṣogbo.

Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun wipe mo lọ layọ mo bọ layọ,



KANSẸLỌ M. A. K. ẸSỌ

On pẹlu awọn ti ijọọa Ijẹṣa ti ma nran lọ lati ṣe ayọwo ilẹ Ijẹṣa to de tosi Ilẹ Oluji. A gbọ pe Oṣemowe Ondo ti pe Ọwa Ileṣa lejọ tori ilẹ na a si tun gbọ pe awọn Ondo nru waya kifi igbo lati ma fi de Ijẹṣa nibẹ Ọpọlọpọ Ijẹṣa ni wọn ti fẹrẹ na pa nibẹ gẹgẹbi a ti gbọ.


## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBOKUN"

| | | | |
|---|---|---|---|
| OJU EWE KINI | | | |
| Igba | 1—12 | 8s. | fun inşi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 7s. | „ „ „ |
| OJU EWE KEJI | | | |
| Igba | 1—12 | 5s | fun inşi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 4s. | „ „ „ |
| OJU EWE KẸTA | | | |
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun inşi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. „ | „ „ |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | „ „ „ |
| OJU EWE KẸJỌ | | | |
| Igba | 1—12 | 6s. | fun inşi.kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 5s. | „ „ „ |

OJU EWE 4, 5, 6, TI 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.

